**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

NO. 124 WEDNESDAY NOVEMBER 18—TUESDAY NOVEMBER 24 1964 KOBO MẸTA 3D

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona

## Bi Ẹgbẹ Itẹsiwaju Parapọ ba wọle idibo:—

# AWO NI OLOTU IJỌBA

## Iku gba ọkọ lọwọ iyawo

NIBITI ọmọkunrin kan ti ọjọ ori rẹ to ọdun mẹtadinlogoji, Afame Zege ti nba iyawo rẹ sọrọ ni Gboko ni agbegbe Tiv ni iranṣẹ iku ti wa baa, ti o si mu lọ si ọrun aremabọ.

Onirohin wa fi ye wa pe nibiti awọn mejeji ti nsọrọ ni idagiri ba de lojiji ti ẹjẹ bẹrẹ si da gọọrọ silẹ lati ẹnu rẹ ati imu rẹ gẹgẹbi igbati omi ba nya lati oju ọrun.

Lẹsẹkẹsẹ ni obinrin na fi ariwo ta ti okiki si gbode kanri sugbọn ki awọn aladugbo to de ibi iṣẹlẹ na ọdọmọkunrin na ti ku bamubamu.

## Ọwọ tẹ Maja

Ọwọ ile ẹjọ kekere kan ni Opopo Tapa ni Eko tẹ Dokita Akinọla Maja ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi nigbati adajọ ile ẹjọ na sọ pe ki ogbologbo arugbo onișegun na, Dokita Maja lọ san adẹjọ pọnun gẹgẹbi owo itanran tabi ki o lọ si ẹwọn osu meji pẹlu iṣẹ aṣekara lori ẹsẹ pe ko san owo ori rẹ fun odidi ọdun marun gedegbe ti o ti kọja sẹhin.

Baba agbalagba na, Dokita Maja ni o ti wa tẹ'e gẹgẹbi 'baba fun ẹgbẹ Afẹnifẹre' ti Naijiria sugbọn Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ti gbọn danu kuro ninu ẹgbẹ na ninu ọdun yi nitori aṣẹsẹsẹ rẹ ninu ẹgbẹ na.

Ẹsun ti ipẹjọ fi kan Dokita Maja ninu ile ẹjọ na nipe Dokita Maja ko fi iwe isiro gbogbo bi owo ti wọ'e fun un ati gbogbo inawo rẹ sọwọ si ile iṣẹ awọn agbowo ori Ijọba Apapọ fun gbogbo ọdun na ti iṣe 1959 titi de 1963.

Nigbati ẹjọ na kọkọ jade ni ile ẹjọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi, Dokita Akinọla Maja gba pe on jẹbi ẹsun ti ileẹjọ fi kan an. Ki adajọ ile ẹjọ na to se idajọ rẹ, babaarugbo na Dokita Maja se awawi ẹjọ rẹ ninu ile ẹjọ na pe on ko ni anfani lati le fi iwe alaye lori isiro inawo ati igbowo wole on sowo gẹgẹbi ofin owo ori, Nitoripe gbogbo iwe isiro owo on ni o ti sọnu lọdọ awọn ọlọpa ni ọdun 1962 ti igbimọ iwadi Coker waiye lori eto ajọ ẹgbẹ NIPC.



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Orișa akunlẹbọ fun Naijiria

## ỌBẸ BA'DI ẸGBẸ ONIKUMỌ

ẸKA ẹgbẹ Afẹnifẹre awọn akẹkọ ni Unifasiti ti Ifẹ sọ ni ilu Ibadan ni ọjọ Ọjọru ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi pe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o wa ninu ọgba ẹwọn nisisiyi ni yio di Olotu Ijọba Apapọ Orilẹede yi ti ajumọṣepọ gbogbo ẹgbẹ Itẹsiwaju orilẹede yi-UPGA ba ti gbẹiyẹ lọwọ gbogbo awọn ẹgbẹ yoku ni orilẹede yi ninu idibo ti o de tan yi.

Ninu iwe ikede kan ti akọwe ẹgbẹ na, Ọgbẹni Wumi Adegbonmire fọwọsi, ti ẹgbẹ na si gbe jade ni Ibadan ni ọjọ na, ẹka ẹgbẹ na ṣe alaye pe erò ọkan ati ireti gbogbo awọn enia ni orilẹede yi ni pe "ki aṣaju atata ti ọgbọn ori rẹ pe perepete — Oloye Awolọwọ" jade kuro ninu ọgba ẹwọn ti o wa nisisiyi.

Awọn akẹkọ na ṣe alaye siwajusi pe ohun irira patapata gba ni yio jẹ lati ri pe ọkan ninu awọn akikanju meji pataki ti nwọn ṣiṣẹ tọsan toru nitori ominira ilẹ Naijiria yio wa ni ipo ẹhin yatọ si ipo Olotu Ijọba orilẹede na.

Nwọn wa ṣe alaye pe "UPGA ti o fi ọrọ idasilẹ Oloye Awolọwọ kun ipolowo idibo ko fi erọ na kun ni ikun awada tabi aṣọjọ rara."

Awọn akẹkọ na wa mu ki o da awọn enia orilẹede yi loju pe akoko na ku yinkinni nisisiyi ti ipe yio dun si wọn pe ki awọn yan enit awọn ba fẹ gẹgẹbi Olotu Ijọba Apapọ orilẹede yi latin Alhaji Balewa ati aṣaju atata, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Ẹka ẹgbẹ na wa fikun pe ti enia ba kiyesi gbogbo iṣeti Oloye Awolọwọ lati ẹhin wa, oluwarẹ yio le sọ nipato pe ti Oloye Awolọwọ ba fi di Olotu Ijọba Apapọ ẹgbẹ Itẹsiwaju—UPGA, ẹtọ ati ikaju iṣẹ ni Ijọba na yio ma wo gba awọn enia si iṣẹ ati ajọ orisirisi pẹlu mọ iṣẹ awọn aṣoju ni ilẹ okere yatọ si ojusaju pẹlu irira ẹlẹyajẹya ti o gbode kankan nisisiyi nipa gbigba awọn enia si awọn ipo na ti a ti duukọ wọn soke yi.

Awọn akẹkọ na wa pari ọrọ na pe "ẹto miran yatọ si gbogbo eyiti awọn ti mẹnuba wọnyi ko le mu ki irẹpọ ti o fẹsẹ mulẹ wa ni orilẹede Naijiria".

ỌRỌ OLOTU:—

## ẸGẸRẸMITI JIBITI (3)

NIGBATI ẹgbẹ Onikumọ Parapọ - Olomi, Dọmọnu, Alaburada ati Ẹlẹja gbe ileri idibo rẹ jade, awọn enia ti ko ba ṣe ayẹwo rẹ yekeyeke yio ro wipe nwọn le sọ oke di ilẹ. Ayẹwo kinnikinni ti fihan pe ojoro nlanla ati jibiti ti o lewu gidigidi ni nwọn gbe kalẹ. Alumọ ati anda ileri ni!

A PE ẹgbẹ Onikumọ Parapọ ni ija lati sọ fun araiye gbọ bi awọn obinrin Naijiria ni ipin ninu ogbu-nduku jibiti na ti nwọn pe ni ileri idibo. Ẹgbẹ Itẹsiwaju Parapọ pese ohunrere fun awọn obinrin orilẹede yi ṣugbọn ẹgbẹ Onikumọ Parapọ fi wọn dagunla. A kẹdun pupọ!

ẸGBẸ Itẹsiwaju Parapọ ni igbagbọ ninu ẹtọ awọn obinrin lati dibo fun tabi duro fun idibo ṣugbọn iru igbagbọ bẹ jẹ majele fun ẹgbẹ Onikumọ Parapọ. Ni Ipinlẹ Ariwa labẹ ẹgbẹ Olomi, awọn obinrin ko ni ẹtọ lati dibo fun tabi duro fun idibo. Kini awawi ẹgbẹ Olomi? "Ẹsin imale ko fun wọn ni anfani".

A KA awawi yi si ti omugọ ati alailoye oṣelu. Ẹsin imale ti Ipinlẹ Ariwa ha dara kọja ti Ẹgypt, Mẹkka, Sudan ati Pakistani? Ṣe bi awọn obinrin ni anfani lati dibo fun ati lati duro fun idibo. Ẹsin imale ti Bello ni Oke Ọya yatọ, o tun ya ijọra paapa.

BI o ba jẹ wipe nitori ẹsin ni ẹgbẹ Olomi ko ṣe fun awọn obinrin Oke Ọya ni ẹtọ wọn, awọn obinrin onigbagbọ Kristi ibẹ nkọ? Ko si awawi mọ, "Ọlọpa" ti o gbe panla ti jẹwọ. Ko si idi miran ju wipe ẹgbẹ Onikumọ parapọ ko fẹran awọn obinrin rara ati pe

(Wo oju ewe kẹjọ)

**Gbadun Ẹmi ẹ pẹlu STAR**




**Maṣe jẹki Dọmọnu da yin nu—Dibo fun UPGA**

